# IROHIN IMỌLẸ

IMỌLẸ ORE AIYE, TẸNI GBOGBO LAWA

No. 719 MONDAY JUNE, 15, 1964 (2D)


## Awọn Obinrin Ọlọja Eko Fẹ Ri Balewa

EKO:— Ninu ipade pajawiri kan ti gbogbo awọn obinrin Ọlọja Eko ṣe ni kutukutu owurọ ijẹta ọjọ Abamẹta ti iṣe ọjọ kẹtala oṣu yi ni gbogbo wọn ṣe ipinnu pe, gbogbo a ọn Obinrin Ọlọja Eko ko ni ta ọja ni owurọ yi gbogbo awọn ni yio si to lọ si ile Alahaji Abubakar Tafawa Balewa lati lọ bẹ Alhaji pe ki o san ẹkunwo owo oṣu fun awọn oṣiṣẹ ki o si jẹki gbogbo wọn o pada lọ si ẹnu iṣẹ wọn kia-kia.

Agbọrọsọ awọn Ọlọja Eko, Iyaafin Abibatu Mọgaji fi ye Oniwe Irohin wa pe, ọja awọn ko ti daada ni ọja mọ, awọn ko ri awọn enia wa ra ọja awọn lọja lati ọjọ ti awọn oṣiṣẹ ti da iṣẹ silẹ.

Abibatu Mọgaji tun sọ pe, agoloiyọ ti awọn ti nra ni tọrọ ti di sisi. Apo gari ti awọn ti nra ni pọnun meji di pọnun meji abọ apo ẹwa ti awọn ti nra si pọnun mẹrin ti di pọnun meje, ju gbogbo rẹ lọ, bi awọn ba ra ọja na, awọn ko ri ẹni wa raa lọja.

Awọn Obinrin na ni nigbati Oṣu ba si pari Ijọba yio sọ pe ki awọn wa san Owo Oṣu Iya Mọṣudi wa bere pe, "Nigbati ọja ko ta ti awọn Oṣiṣẹ ko lọ si ẹnu iṣẹ nibo ni a ti ri Owo san ?"

Ni ipari, awọn Obinrin na sọ pe bi Ijọba ko ba jẹki awọn Oṣiṣẹ pada si ẹnu iṣẹ wọn loni gbogbo awọn Obinrin Ọlọja Eko ni yio lọ foju kan Balewa ninu ile rẹ ni Owurọ yi.

# HA ! Ẹ BA WA YỌ !! AWA OṢIṢẸ JA'GUN MOLU !!!

EKO:— Idunnu ṣubu lu ayọ, ayọ ṣubu lu oyin nigbati irohin de si etigbọ gbogbo awọn oṣiṣẹ pe, Apapọ Ijọba Naijiria ti gba lati san ẹkunwo owo - oṣu ati owo - ọya oṣu mẹsan fun gbogbo awọn oṣiṣẹ jakejado ilẹ Naijiria gẹgẹbi Igbimọ oluwadi Morgan ti ṣe pa-laṣẹ fun Ijọba.



Aworan oke yi ni ti awọn oṣiṣẹ ti nwọn nyọ ayọ ẹkunwo owo-oṣu

Ninu ipade Alabẹṣekele kan ti awọn asiwaju ẹgbẹ awọn oṣiṣẹ jijọ ṣepọ pẹlu awọn Aṣoju ati Alaṣẹ Apapọ Ijọba Naijiria ni ọjọ Abamẹta ti iṣe ọjọ kẹtala oṣo yi, Ijọba gba pe awọn yio farama gbogbo ohun ti awọn oṣiṣẹ fẹ ki Ijọba ṣe fun awọn patapata.

Lẹhinna ni awọn alaṣẹ Ijọba na wa rọ gbogbo awọn oṣiṣẹ patapata pe ki nwọn jọwọ fiyedenu ki nwọn pada si ẹnu iṣẹ wọn kia-kia ki awọn iṣẹ Ijọba maṣe tun bajẹ lọ siwaju ju eyiti o ti bajẹ yi lọ.

Ṣugbọn awọn Aṣiwaju ẹgbẹ oṣiṣẹ ti nwọn wa ninu ipade na fi ye Ijọba pe, ki awọn to lọ si ẹnu iṣẹ awọn gẹgẹbi alaye Ijọba awọn fẹ sọ awọn ọrọ mẹfa kan eyiti o dabi ẹnipe o le mu idiwọ wa fun awọn " A kunlẹ a fi apo rọ a naro tan ọwọ ko to mọ."

Lẹhinna ni nwọn wa ṣe alaye pe, ki Ijọba gba ọran na ro fun awọn, bi Ijọba ko ba gba ọrọ na ro fun awọn awọn oṣiṣẹ ko ni bẹrẹ iṣẹ wọn pada.

Awọn Asiwaju ẹgbẹ oṣiṣẹ na sọ pe, o le ni ẹgbẹdogun (50,000) awọn oṣiṣẹ ti nwọn nṣiṣẹ labẹ awọn oyinbo oniṣowo ti nwọn si ti fun ni iwe idaduro lẹnu iṣẹ wọn pe, " ko si iṣẹ fun wọn mọ, ki nwọn lọ wa iṣẹ si ibomiran nitoripe, nwọn binu da iṣẹ silẹ.

Lẹhinna ni awọn Asiwaju oṣiṣẹ na wa sọ ọna mẹfẹfa ni ti awọn nfẹ, ki Ijọba si fọwọ si i ki awọn oṣiṣẹ to le bẹrẹ iṣẹ wọn pada.

(1) Ijọba ko gbọdọ ṣe inunibini si awọn oṣiṣẹ lẹhinti nwọn ba bẹrẹ iṣẹ wọn.

(2) Gbogbo awọn ti Ijọba ti fun ni iwe aṣẹ pe, ko si iṣẹ mọ ni ki nwọn gba pada lọwọ wọn.

(3) Gbogbo awọn oṣiṣẹ ni yio gba oju owo wọn ni ipari oṣu ti Ijọba ati awọn oyinbo onisowo ko ni gbọdọ yọ owo igbati nwọn ko wa si ibi iṣẹ ninu owo oṣu wọn.

(4) Ni kutukutu owurọ yi ki Apapọ Ijọba Naijiria pe ipade kan ni oni ninu eyiti gbogbo awọn Oyinbo oniṣowo ati awọn Asiwaju ẹgbẹ oṣiṣẹ yio ti sọrọ pẹlu ituninubi larin ara wọn.

(5) Atipe gbogbo ọrọ ti awọn yio joko sọ loni yi ni lori eto ẹkunwo owo-oṣu eyiti Igbimọ Morgan palaṣe pe, ki Ijọba san fun awọn oṣiṣẹ.

(6) Ijọba ati awọn oniṣowo ko gbọdọ sọ ọrọ awa yi kan lati da ẹnikan duro lẹnu iṣẹ wọn lori ọrọ yi. Bi Ijọba ba ti le fi ara mọ gbogbo awọn eto mẹfẹfa ti awọn sọ silẹ yi, awọn gẹgẹbi Asiwaju ẹgbẹ oṣiṣẹ gba, awọn ṣi tun faramọ pe, ki awọn oṣiṣẹ jakejado orilẹede yi pada si ẹnu iṣẹ wọn lafarabara.

Nigbati nwọn sọ awọn ọrọwọnyi fun Ijọba tan, Ijọba gba lati faramọ gbogbo eto na gẹgẹbi awọn Aṣiwaju ẹgbẹ oṣiṣẹ ti wi.

Lẹhinna ni Alhaji Haruna Popoọla Adebọla wa kọ gbogbo rẹ sinu iwe kan fun Ijọba gbogbo wọn si fọwọ sinu iwe na.

Awọn ti wọn ṣe Agbọrọsọ fun awọn ẹgbẹ oṣiṣẹ ninu ipade na ti wọn si fi ọwọ si iwe adehun na ni Ọgbẹni W. O.Goodluck, Ọgbẹni N.Chukura, Alhaji H. P. Adebọla, Ọgbẹni S. U Bassey , Ọgbẹni L. L. Borha, Ọgbẹni Gogo Chu Nzeribe, Ọgbẹni E C Okon Acnamba ati Ọgbẹni E.N. Okongwu.

Awọn ti nwọn ṣe Aṣoju ati Agbọrọsọ fun Apapọ Ijọba ninu ipade na ni. Oloye F S. Okotiẹ - Ẹbọh, Dokita K. O. Mbadiwe Ọgbẹni J. C. Ọbande, Alhaji Waziri Ibrahim, ati oloye J.M. Johnson.

Wo oju ewe kẹfa.

# YẸYẸNATU

## ONIYEYE EKO

Olotu:- Hello, Yẹyẹnatu

Yẹyẹnatu:- Hẹllo yın o jare Olotu

Olotu:- Ṣe ko si nkan?

Yẹyẹnatu:- Ti kini fi ṣe?

Olotu:- Ija ni? Bi o ṣe nsọrọ yi ni.

Yẹyẹnatu:- Ṣebi ẹ ri bi ojo ti pa mi ti gbogbo ara mi tutu.

Olotu:- Hẹn, on na ni mo ṣe nbere pe ṣe ko si nkan.

Yẹyẹnatu:- Ti ko ba si nkan emi i ba ko sinu ojo? Gbogbo rẹ ko tilẹ dun mi bi wipe aṣọ ti nwọn pe fun ode irọlẹ lojo ti pa mọ mi lọrun yi.

Olotu:- Iwọ na ṣe jade ninu ojo.

Yẹyẹnatu:- Ẹjọ mi kọ

Olotu:- Ẹjọ tani?

Yẹyẹnatu:- Ẹjọ ohun to balewa ni.

Olotu: Kılo balewa kẹ?

Yẹyẹnatu:- Tafa Balewa ni

Olotu:- Bawo?

Yẹyẹnatu:- Ohun to sọ si awọn oṣiṣẹ lo da ija silẹ laarin Suberu ati iyawo rẹ

Olotu:- Ija kẹ?

Yẹyẹnatu:- Ti ọlọpa ti ko wọn.

Olotu:- Hẹ, ṣebi ija ọkọ ati aya ni

Yẹyẹnatu: Ọtọ ma ni ẹjọ ti awọn ọlọpa tun nba ọkọ rẹ ro

Olotu:- O jale ni tabi o pania?

Yẹyẹnatu:- Nwọn ni o nkọ iyawo rẹ si ijọba.

Olotu;- Bawo kẹ?

Yẹyẹnatu:- Nigbati gbogbo oṣiṣẹ da iṣẹ silẹ, Iyawo Suberu ko da iṣẹ silẹ

Olotu:- Kini o sọ pe o de?

Yẹyẹnatu:- O ni, ekini on ko fẹ ki iṣẹ on bọ, ekeji, on fẹ ṣe oju boya awọn ọga a gbe on ga

Olotu:- O ma gọ o

Yeyẹnatu Suberu ba binu

Olotu:- Ṣe Suberu sọ pe ohun ko le gbọ bukata lori rẹ ni?

Yẹyẹnatu:- O ni nigbati on sọ fun Suberu pe on fe ra aṣọ oku Olowogbowo ke da on lohun. O ni bi on ko ba lọ sibi iṣẹ bawo ni on yio ṣe rowo gba lopin oṣu?

Olotu:- Ọran ni ki ọkọ rẹ ra'aṣọ oku fun ni?

Yẹyẹnatu: Haba, ọran ni ki ọkọ rasọ ẹbi o Ọkọ ti ko ba le ṣe bẹ nisisiyi ko to ọkọ ṣe kẹ. Iyawo Suberu tilẹ gọ nitori ẹkan loṣu lo nra aṣọ ẹbi, Awa bayi ọsẹ-ọsẹ ni.

Olotu:- Ọkọ rẹ ko yi luu to

Yẹyẹnatu:- Hẹn ṣebi awọn ọlọpa si ti ti i mọ le ti nwọn nba ṣe ẹjọ pe o nko awọn enia si Ijọ.

Olotu;- Bawo ni paapa?

Yẹyẹnatu:- Nigbati Iyawo rẹ ni on nlọ sibi iṣẹ o luu o ni ko gbọdọ lọ, ṣugbọn Iyawo rẹ gba oju window bẹ sita lo ba lọ. Nigbati o to wakati bi meji ni Suberu ba gbọna ibi iṣẹ wọn, o wọle o bẹrẹsi lu iyawo rẹ, o nwọọ jade were ọlọpa ati ṣoja ba ki i mọlẹ ni nwọn ba lu lu lu titi nwọn fi ti i mọle

Olotu: Kini iyawo rẹ wa nṣe?

Yẹyẹnatu;- O nke, o nbẹ, ọlọpa ni

Olotu:- Ṣe nwọn fi i silẹ

Yẹyẹnatu:- Nwọn ko tilẹ woju rẹ

Olotu:- O maṣe o, ibẹ lo ti nbọ yi?

Yẹyẹnatu:- Ẹjọ wọn ti de kootu

Olotu:— Ha, bawo ni Suberu yio ha ṣe rowo gba lọya?

Yẹyẹnatu:— Awọn ẹgbẹ osiṣẹ ti gba lọya fun

Olotu;— Ṣebi tailor ni Suberu nṣe o wa ninu ẹgbẹ oṣiṣẹ ni?

Yẹyẹnatu:— Ko si. Awọn ẹgbẹ oṣiṣẹ kan fẹ ran lọwọ ni

Olotu:— Igba wo ni nwọn fẹ dajọ na wayi?

Yẹyẹnatu:— Ọlọrun lo mọ Ṣugbọn nwọn ti sọ fun iyawo rẹ pe koyara ma lọ sibi iṣẹ kiakia.

Olotu:— Ṣe o si nlọ?

Yẹyẹnatu:- Iyawo ni on ko le fi Suberu si itimọle ki on ma a lọ sibi iṣẹ nitorina ki nwọn jọwọ nitori Ọlọrun ti on mọ ile.

Olotu:— Ṣe nwọn si ti i mọle

Yẹyẹnatu;— Nwọn ro pe iyawo nṣire. Adajọ ni "Yes, e ti i mọle pẹlu ọkọ re.

Olotu: Ha nwọn fẹ fun wọn ni iyara nibẹ niyẹn

Yẹyẹnatu:- Ni iyawo Su—beru ba kunlẹ o dupẹ lọwọ adajọ, o si i wọ iyara iti mọle pẹlu ọkọ rẹ.

Olotu:...... Ha ha ha.

Yẹyẹnatu:...... Loju ba ti adajọ, o ni tooto ọrọ ọkọ ati aya ma a le o Ẹ ṣi ilẹkun fun wọn

Olotu:- O ni ki nwọn da wọn silẹ?

Yẹyẹnatu:- Yẹs kẹ, o ni ki nwọn ma a lọ sile, ṣugbọn ki Suberu tun wa si kootu lọjọ mẹjọ

Olotu:...... Iyawo rẹ ko ni yẹn kẹ

Yẹyẹnatu:...... Nitori iyẹn lo ṣe nsọkun O si ti kọ lati lọ ṣiṣẹ nisisiyi o ni bo ba ṣe ẹwọn on ati Suberu jọ nlọ ni i

Olotu:- Ṣẹ iyẹn lo je ki ojo pa iwọ na to dabi ekute to ko ṣomi.

Yẹyẹnatu: Ṣe iyẹn lo nṣe ẹnyin na ti ẹdabi ẹniti owo oṣu rẹ ko to na

Olotu:- O fẹ bu mi ni?

Yẹyẹnatu—Ẹnyn nafẹ bu mini

Olotu... Rara o. Mo ni ṣe ọrọ strik na ni o jẹ ki oko si ojo

Yẹyẹnatu—Hẹn, mo ni ṣe ọrọ Sikire na lo jẹ ki ẹnyin na da bi ẹniti owo oṣu rẹ ko to na?

Olotu:-Odara maa ma bu mi

Yẹyẹnatu—Odara odabọ sir

# Mọsalasi Njo-na Alhaji Njo

Lati ọwọ AFỌLABI ỌLABINTAN

"Baa san Alah ba" ni gbogbo wọn nwi,
Bina ti njo teefin gbode kan
Tiya nfọwọ kan gbọmọ ọwọ to nfosi fagba
Igbati Mọsalasi njo, ti Lemọmu nkọrin.

Bi owe bi owe la nlu agidigbo
Ẹni lọgbọn lori a foye momu ayan
Omugọ a yara ma a tapa laimoye
Dindin a ma a nawo laimoye.

Ina njo lọtun, Alhaji njo dun losi
O ni bina njo le bi ko jo, oran tan,
Bina jo Mọsalasi ko jo titi deeru
Ko sa jina ko ma dọdọ on, iyan ni pataki.

Gbogbo ilu nsọkun kabiyesi nf'ẹhin
Ebi npa ilu, oloye nlabẹ lawujọ
Tani ko mọ pe egun lọga njẹ mọ'yan
Tani ko mọ pe igberaga ni nṣiwaju iparun.

Mọsalasi jo titi musulumi adugbo na a,
Lemọmu Kina sile, mosa ati saka dopin
Ina jo titi ko sai jo ọmọ enia
Sibẹsibẹ Alhaji ko wẹhin, jijo lo njo ni irẹ

Mo de 'le Sanni mo ni "Bawo"?
Mo de 'le Taju mo ni "Họwu"
Nwọn ni ki npẹnumọ, soja nbọ
Nwọn ni nṣọra ki nma gba igi

Mo ni "ewo tun ni ṣọja igba ile njo?
Ewo ni tafunja-ma-pọmọ ti nhalẹ kiri,"
Nwọn ni "Lemọmu lo sọ wọn d'ọga-
Ntori ati f'ebi pọmọ kekere
Ntori ati p'agbalagba l'ọda
Ntori ati s'ọmọde d'ẹru
Ntori ati s'agba d'ọdẹ
Ntori ati sọra rẹ da'Anabi lawujọ gbogbo wa"

**E ma a Ka Iwe Irohin Imọlẹ Lojojumọ Ki ẹ si ma a Polowo Ọja Nyin Sinu Rẹ Pẹlu**

# Kobiowu Ni Yio Jẹ Olubadan Titun

IBADAN:- Ni ọjọ Aje ti iṣe ọjọ ekinni oṣu ni irohin de ọdọ wa lati Ibadan pe Oloye Yesufu Kobiowu ti o jẹ Ọtun Olubadan

Oloye Kobiowu n i y i o rọpo Ọba I s s ac Babalọla Akinyẹle ti o ku larin ọ s ẹ to kọja Yiyan Oloye Kobiowu gẹgẹbi ẹniti yio jẹ Olubadan jade lati ẹnu Oloye D. T. Akinbiyi lẹhin ipade kan ti awọn lọbalọba i l u Ibadan ṣe ni ọjọ Aje ti iṣe ọjọ kinni oṣu y i . A w ọ n Ọba na ni o wa gẹgẹbi afọba jẹ ni Ibadan.

Oloye Akinbiyi f i y e oniroh n wa pe f i f i Oloye Kobiowu jẹ Ọba si tọna, Oloye Kobiowu jẹ oye Ọtun Olubadan ni ọjọ kọkanla oşu keji ọdun 1953. Ẹ u l ọ d u n mẹrindinlọgọta n i Oloye na iṣe.

Oloye Kobiowu si ti wa gẹgẹbi ọmọ ile Igbimọ lọbalọba ti Ipinlẹ Iwọ Orun Naijiria lati ọdun 1957. Nwọn si fi jẹ oye gẹgẹbi oloye kekere ni ọdun 1937, Ni ọdun 1957, oloye Kobiowu lọ si ilu Oyinbo gẹgẹbi ọkan ninu awọn to jẹ asoju Ijọba Ipinlẹ Iwọ Orun nipa eto iṣẹ ọgbin,

Oloye si tun ṣe iṣẹ gẹgẹbi adajọ ni ile ẹ o Ibile ti Ibadan,

Irohin tun de owọ wa lati Ibadan pe ifijoye Olubadan oloye Kobiowu ki yio bọ si mọ ni ọjọ Ẹti ti iṣe ọjọ karun osu yi gẹgẹbi a ti gbọ tẹlẹ Akọwe agba ti Ijọba Ibil ilu Ibadan ọgbẹni Ajibọla fi ye onirohin wa pe awọn Ijọba Ipinlẹ Iwọ Orun Naijiria ni lati ṣe awọn eto kan ki nwọn to fi oloye Kobiowu joye. A ko ti mọ ọjọ ti nwọn yio fi joye bayi

## YẸ IRAWỌ RẸ WO

AQUARIUS (Jan 20 - Feb 18) Odabi ẹni wipe aṣeju rẹ pọju, ṣugbọn bi o ti wu ki o ri, o yẹ ki o ma ronu wo ki ọrọ to jade lẹnu rẹ, Iwọ yo gbọ irohin pataki kan loni, oni dara fun ẹgbẹ ati ode wiwọ.

PISCES (Feb 19-Mar 20) Aşeju rẹ pọ jọjọ on lo jẹki arẹ ma ṣe o. Bi o ba feti silẹ si imọran atata, ọna rẹ yio sunwọn, ẹnikan ti o pade loju ọna lo fa sababi ailera ti o nyọ ọ lẹnu.

ARIES (Mar 21-April 19) Yara kankan ninu ọro to ba ṣe pataki, bi bẹkọ awọn ẹbi rẹ yio da si ọ lọrun, Agidi ọkan rẹ yio pọ tobẹ ti iwọ ko fi ni le tẹriba fun aṣẹ ọ a rẹ, tabi ẹgbẹ rẹ kan.

TAURUS (April 20 May 20) Ina arisiki rẹ njo, geregere, yio si wa bẹ fun akoko kan. Bi o ba ri nkan titun maşe sare ra a, Ro owo ki o to ra a Iṣẹ rẹ yio ma lọ deedee.

GEMINI (May 21 - June 21) Maşe fi ohun ti o ni lati ṣe loni silẹ di ọla nitori Ọlọrun lo mọ ilẹ ti yio mọ lọla. Bọwọ fun agba ati ọga rẹ. Ifẹ larin iwọ pẹlu obinrin koiti daju, sinẹ, iṣẹ rẹ yio ma lọ geregere

CANCER (June 22 - July 22) Iṣẹ rẹ ati ọrọ ara rẹ yio ma lọ daradara, oni li ọjọ to dara lati ṣe adehun pẹlu enia.

LEO (July 23 - Aug 22) Ọrọ inu ile rẹ nda ọ lamu, maṣe tete ma jẹki ọrọ jade lẹnu rẹ, nṣe ni ki o kọkọ ma wadi ọrọ wo na, bi o ti wu ki o ri, iṣẹ rẹ yio ma lọ siwaju.

VIRGO (Aug 23 - Sept 22) Ara rẹ le. ọgbọn ori rẹ si pe de ipo ti o rope ohunkohun ti o ba de o ti l gbara lati ṣe eto rẹ. Iwọ le riwe gba tabi ki o lọ si ajo kan ti yio gbe ire wa ba ọ.

LIBRA (Sept 23 - Oct 23) Gbogbo ohun ti o ba dawọle ni şişe, ire ni iwọ yio ma ba pade nibẹ, Ẹnikan yio wa bẹ ọ wo lairotẹlẹ, ire yio wa larin ẹgbẹ nyin. Ọrọ ti ko ni lari kan yio da ija silẹ.

SCORPIO (Oct 24-Nov 22) Iṣẹ yio pọ fun ọ loni yio si ma mu ere wa fun ọ, Iwọ yio ma ri owo na bẹni iwọ yio ma ri obinrin fe.

SAGITTARIUS (Nov 23-Dec 21) Şi fi ọrọ ara rẹ silẹ na, ki o mojuto iṣẹ rẹ wahala kan wa larin awọn ẹgbẹ rẹ tabi awọn ẹbi rẹ ti ẹnikini kọ lati gbẹ ti ẹnikeji nitori ohun kan ti a ṣe ti o ko jẹki ẹnikeji mọ tẹlẹ nipa rẹ.

CAPRICORN (Dec 22-Jan 19) Maşe wa mọto ni iwa kuwa loni ki o si ba awọn obi rẹ pari ija, ki o si fun wọn ni imọran titunmiran.

BI O BA NI

Iwe—Tite

FUN

Lilo nibi Iṣẹ rẹ tabi orişirişi iwe itufọ tabi ijade Oku

ATI

Iwe gbeyawo

TETE KỌWE SI ILE—IṢẸ—ẸRỌ ITẸWE

Modupẹ Printing Press

16 Bamgboṣe Street, P. O. Box 1495

Telephone: 21985, Lagos.

KETEKETE NI ẸRỌ ITẸWE WA NHAN

OWO PỌKU NI A SI AGBA

IROHIN KO TO AFOJUBA

*Dan wa we lẹẹkansoso ko ri iyatọ*

## Ibanujẹ Tabi Ironu Rẹ de Opin Ayọ De

Bere Ojulowo Egbogi awọn Faranse gidi ti a npe ni

## 'CORSIVER'S



Ojulowo ati Ajẹbidan Atamatase Egbogi ti a ṣe ni pataki Fun „ARỌN KINIṢA" tabi LATANATAN" ti o ma mu idiwọ wa fun Obinrin lati Fẹralu tabi lati ma ṣe abiyamọ meji rẹ kosi kakiri igboro ilu Eko. Lẹhin ti o ba lo egbogi arọn yi tan ti inu-riru, aya ririn, ẹhin didun tabi aikoto ẹjẹ lara, ẹjẹ dudu ibadi gige tabi sisan ba nyọ ọ lẹnu ibẹsibẹ bere ojulowo egbogi ti awọn Oyinbo ṣe nipataki fun AJO "OBINRIN" ti awọn amodi wọnyi ba nyọ lẹnu ti wọn npe ni egbogi na ojẹ ni ṣọbu awọn.

Waterloo Stores
8, Palm Church Street, Lagos.
Phone:- 2287 Nigeria, (Ọja Ita Faji Lagos.)

ADEDUN CHEMIST
14. Wakeman Street Lagos

NIGERIAN MEDICINE STORE
Tinubu Square Lagos.

# Eyi ni awọn ọjọ Oja Ilẹ Yoruba

## ỌJỌ AJE JUNE 15 (MONDAY)

| ILU | ORUKỌ AWỌN |
| --- | --- |
| EKO ATI AGBEGBE RẸ | Ọban-Eko, Ojuwoye Ikosi, Ẹpẹ |
| ABEOKUTA | Atan Agbado, Ifọ Itori, Itoku Isabọ, Ọdẹda, Ibara, Kila, |
| IBADAN | Fẹdẹgbo, Oyedeji, Ogburo, Ẹgbẹ |
| IJEBU | Babalokuta, Ijaiye Orile. Ilishan, Iṣara, Imodi. |
| IJESHA | Ẹpẹ, Ilọba, Imuroko, Erinmọ. |
| EGBADO | Aiyetoro, Ado-Odo. |
| EKITI | Egosi, Odo-Aiyedun. |

## ỌJỌ IṢẸGUN JUNE 16 (TUESDAY)

| ILU | ORUKỌ AWỌN ỌJA |
| --- | --- |
| EKO ATI AGBEGBE RẸ, | Mushin, |
| ABẸOKUTA | Ọtta, Abalabi, Ṣodẹkẹ, Omida Ilawọ |
| IBADAN | Ituko, Sojukonko, Tọwọbowo Temidire |
| IJẸBU | Ikẹnnẹ, Ọkun—Ọwa, Ẹruwọn, Omu. Mamu |
| JẸSHA | Osnu, Itagun, Odogbo, Idoko Iloko |
| ẸGBADO | Igbogila Ijọun, Imasai Owode |
| EKITI | Oke-Aiyedun, Ikọle |

## ỌJỌ'RU JUNE 17 (WEDNESDAY)

| ILU | ORUKỌ AWỌN ỌJA |
| --- | --- |
| EKO ATI AGBEGBE RẸ | Ikẹja, Agege Ebute-Ero Ọjọ Ajido |
| ABẸOKUTA | Lafẹnwa, Ọbada, Ọba, Kajọla Ajegunlẹ, Idọgọ, Olodo. |
| IBADAN | Lalupọn, Ajegunle, Owode Igbo-Ọra |
| IJẸBU | Ibẹfun, Atikori, Imushin, Agọ-Iwoye, Ijẹbu-Ijẹsha, Iṣara, Imope |
| IJẸSHA | Iwara Ejiro, Odo, Ibokun Ijẹbu-Ijẹsha |
| ẸGBADO | Lasilọ-Idiẹmi |
| EKITI | Okemẹsi, Ifaki. |

## ỌJỌ ỌJỌBỌ JUNE 18 (THURSDAY)

| ILU | ORUKỌ AWỌN ỌJA |
| --- | --- |
| EKO ATI AGBEGBE RẸ | Oyingbo. |
| ABẸOKUTA | Ijoko, Bẹrẹkodo, Aṣu, Wasinmi Owode |
| IBADAN | Akeroro, Idọfin, Lagun Ṣagbẹ, Ogunjau, Mọlete, |
| IJẸBU | Aiyepe, Shogamu, Itaoṣu, Ogere Irolu, Itele, Ode-Rẹmọ, Oyingbo |
| JẸSHA | Ibodi, Ibode, Kajọla, Imẹsi Ile |
| Ẹ GBADO | Alagba, Ilaro, Ọja-Ọdan, Sunwa Iboro, |
| E KITI | Ilogbo Ishan. |

## ỌJỌ ẸTI JUNE 19 FRIDAY

| ILU | ORUKỌ AWỌN ỌJA |
| --- | --- |
| EKO ATI AGBEGBE RẸ | Ọbun-Eko, Ojuwoye, |
| ABẸOKUTA | Atan, Agbado. Ifọ, Itori, Itoku Isabọ, Ọdẹda, Ibara, Kila |
| IBADAN | Fẹdẹgbọ, Oyedeji, Ẹgbẹda, Baba lokuta' Ijaiye-Orile |
| IJẸBU | Ilishan, Odogbolu, Atan, Imọpe ṣara, Imodi, Ishan, Akẹsan, |
| IJẸSHA | Ẹpẹ, Ilọba, Imuroko, Erinmọọ Ilaṣẹ, Iperindo |
| ẸGBADO | Aiyetoro, Ado Odo |
| EKITI | Egosi, Odo-Aiyedun |

## ỌJỌ ABAMẸTA JUNE 20 (SATURDAY)

| ILU | ORUKỌ AWỌN ỌJA |
| --- | --- |
| EKO ATI AGBEGBE RẸ | Mushin Badagry |
| ABẸOKUTA | Ọtta, Abalabi, Ṣodẹkọ Omida Ilawọ |
| IBADAN | Itoko, Ṣojukonko Tọwọbowo Temidire |
| IJẸBU | Ikẹnnẹ, Ọkun-Ọwa Eruwn Omu Mamu |
| IJẸSHA | Oshu, Itagun, Odogbo Idokọ Iloko |
| ẸGBADO | Igbogila, Ijọun, Imasai, Owode |
| EKITI | Oke—Aiyedun, Ikọle |

## ỌJỌ AIKU JUNE 21 (SUNDAY)

| ILU | ORUKỌ AWỌN ỌJA |
| --- | --- |
| EKO ATI AGBEGBE RẸ | Ikẹja, Agege, Ebute—Ikorodu |
| ABẸOKUTA | Lafenwa, Ọbada, Ọba, Kajọla Ajegunlẹ, Idọgọ Olodo |
| IBADAN | Lalupọn, Ajegunlẹ Owode Igbo-Igbo-Ọra |
| IJẸBU | Ibẹfun, Atikori, Imushin, Agọ-Iwoye, Ijẹbu-Ijẹsha, Iṣara, Imodi |
| IJẸSHA | Ijẹbu-Ijẹsha |
| ẸGBADO | Iwara, Ejiro, Odo, Ibokun, Lasilo, Idiẹmi |
| EKITI | Okemesi Ifaki |

## ỌJỌ AJE JUNE 22 (MONDAY)

| ILU | ORUKỌ AWỌN ỌJA |
| --- | --- |
| EKO ATI AGBEGBE RẸ | Oyingbo Ejinrin |
| ABẸOKUTA | Ijoko Ibẹrẹkodo, Asu, Wasinmi Owode |
| IBADAN | Akẹroro, Idọfin, Lagun, Sagb Ogu nlana, Mọlete |
| IJẸBU | Aiyepe, Sagamu, Itaosu, Ogere Irolu, Itele, Ode-Rẹmọ |
| IJẸSHA | Ibodi, Ibode, Kajọla, Imẹsi Ile Alagba, Ilaro, Ọja-Ọdan, Su-wa, Iboro |
| ẸGBADO | |
| EKITI | Ilogbo, Ishan |

# IROHIN KAKIRI AGBAIYE

Lati ọwọ EJON'GBORO

### MONTANA

Ọgbọn enia ni ugbara ojo gbe lọ ti o si sọ enia mejila di alaisan nigbati ojo nla kan bẹrẹsi irọ ninu ọsẹ ti o kọja yi.

### KẸNYA

Ile Igbimọ Aṣofin Ijọba ti ṣe ofin tuntun kan pe, ẹniti o ba ji kẹtẹkẹtẹ gbe ninu ilu na yio wẹwọn ọdun mẹrinla.

### VIENTIANE

Idaamu nla ba gbogbo enia nigbati ija igboro kan bẹsilẹ ti enia marundinlogoji ku bamubamu ti ọpọlọpọ enia ti nwọn farapa si wa ni ile iwosan nisisiyi,

### ITALY

Enia mẹjọ lo ku bamubamu ti Ijọba si nwa enia meje nisisiyi ninu Ijamba nla kan ti o ṣẹlẹ larin ilu ninu ọsẹ ti o kọja yi.

### MOSCOW

Iyaafin Andrian Nikolayer ti o fo yi aiye po loke-Ọrun fun ọjọ mẹrin bi ọmọbinrin kan ninu ọsẹ ti o kọja yi,

### SALISBURY

Ọgọrun (100) awọn ẹlẹwọn ni nwọn ti binu da iṣẹ silẹ ti nwọn ko si jẹun nitoripe nwọn sọ pe onjẹ ti Ijọba nfun awọn jẹ ko daa fun ọmọ enia lati ma a jẹ.

### ONITSHA

Ọkunrin kan Joseph Onran ẹni ọdun mejidinlogun ni awọn Ọlọṣa kan ta nibọn nigbati ko jẹki nwọn o ko ẹru ninu ile rẹ, awọn Dokita ti yọ ọta ibọn mẹrin ni agbari ọkunrin na,

### IBADAN

Adajọ Ile ejọ kekere Ibadan ṣe idajọ pe ki ẹdaran kan, Jimọh Akanji o lọ si ẹwọn oṣu mejidinlogun nitoripe o ji agutan kan gbe.

### SALISBURY

Ọgbẹni Davies, adajọ Agba ile ẹjọ giga ti ṣe idajọ iku fun awọn " Iya Ajẹ" meji, nitoripe wọn pa ọmọde kan ninu ilu n a ki ọja wọn le ma ta daada,

### SCOTLAND

Jinijini dapo gbogbo enia nigbati Ile pẹtẹsi kan njona, ti enia mẹrin ku bamubamu ti enia mẹriu si farapa awọn Ọlọpa ti gbe gbogbo won lọ si Ile-iwosan,wọn si nwadi ohunti o fa ina.

### IJỌRA

Awọn Ọlọpa ti mu Ọkunrin kan ti o wọ aṣọ daradara ti osi nfi ori tọ opo waya lọsi Ile aisan nigbati Ọkunrin na fẹ pa ararẹ awọn Ọlọpa ko mọ ohunti o ṣe e

# IROHIN IMOLE

IMOLẸ ỌRẸ AIYE, TẸNI GBOGBO LAWA

No, 719 MONDAY, JUNE 15, 1964 (2D


## Obinrin Kan Kọ Ọmọ Rẹ Si Lẹ !

OWERRI:- Ọrọ di wo mi ngwo ọ nigbati ọdọmọdebinrin kan bi ọmọ tuntun kan tan ti o si sọ fun awọn oluranlọwọ Dokita ati Alamọjuto awọn Abiyamọ pe on fẹ sare lọ sọ fun awọn enia on pe on ti bimọ ti awọn si fun obinrin na laye ti ko si pada sinu Ile Iwosan na mọ ni ọjọ Abamẹta ti iṣe ọjọ kẹtala oṣu yi.

Ọkan ninu awọn Olutọju awọn Abiyamọ Ile iwosan na ṣe alaye fun oniwe irohin wa pe, ni ọjọ kẹwa oṣu yi ni obinrin na wa si Ile iwosan nigbati o fẹ bimọ, nigbati o si di ọjọ kẹta ti o i de Ile iwosan na ni o ba bi ọmọkunrin kan.

Nigbati Obinrin na bimọ tan ni awọn ba toju ọmọ na awọn si paṣẹ pe ki o lọ sun ti ọmọ rẹ ni ori ibusun rẹ ti ọmọ rẹ ṣugbọn Obinrin na kọ lati sun ti ọmọ rẹ o si wa tọrọ aye pe on nlọ sọ fun awọn enia ki on si pada nisisiyi

Awọn enia na si paṣẹ pe ki o tete yara lọ sọ fun awọn enia rẹ ki nwọn o le ba gbọ ṣugbọn nigbati Obinrin na lọ tan ko si tun pada wa Ile Iwosan na mọ o fi ọmọ rẹ silẹ nibẹ.

Nigbati awọn alaṣẹ na reti rẹ titi ti awọn ko si ri i titi ilẹ ọjọ na fi ṣu, ni nwọn ba ranṣẹ si awọn Ọlọpa lati wa ba wọn wa iya ọmọ na Obinrin na ko fi adirẹsi ile rẹ silẹ ati ibiti o ti wa. Alafia ni ọmọ na wa, nwọn ntọju rẹ ṣugbọn awọn Ọlọpa nwa Obirin na, ti nwọn ba si ti ri ẹ o ma a gbọ.

## Ha ! E Ba Wa Yọ !! Awa Oṣiṣẹ Jagun Mola !!!

Lati oju ewe kini

IPADABỌ

Irohin fi ye wa pe lẹhin igbati Ijọba ti fi ọwọ si iwe adehun na tan, ni awọn aṣiwaju ẹgbẹ awọn oṣiṣẹ ba ranṣẹ si gbogbo awọn oṣiṣẹ ni Ipinlẹ pe ki gbo gbo wọn pada si ẹnu iṣẹ wọn ni owurọ yi.

Gbogbo awọn Aṣiwaju ẹgbẹ awọn Oṣiṣẹ ni Ipinlẹ kọọkan ni nwọn ti sọ wipe, ki awọn Oṣiṣẹ wọn o maṣe pada si ẹnu iṣẹ titi ti aṣẹ yio fi de lati Eko.

Awọn enia na tun sọ fun awọn Oṣiṣẹ pe, ki nwọn o maṣe gbọ ifilọ "irọ" ti ẹrọ-asọrọmagbesi nṣe ni ojojumọ pe awọn Oṣiṣẹ kan ti pada si ẹnu iṣẹ wọn, nwọn ni ifilọ na ki iṣe otitọ, ṣugbọn awọn ko le ba awọn Oṣiṣẹ Ile iṣẹ na wi, nitoripe, "Iṣẹ ti Ijọba ran wọn ni nwọn nṣẹ"

ADANU

Irohin ti ye wa pe, owo ti Apapọ Ijọba ti padanu rẹ lẹnu igbati awọn oṣiṣẹ da iṣẹ silẹ yi ti le ni adajọ ọkẹ pọun (£14, 000, 000),

Irohin fi ye wa pe, odidi ọjọ mẹrinla ni awọn oṣiṣẹ fi da iṣẹ silẹ ti nwọn ko si fi ọwọ kan iṣẹ ṣe lati ọjọ na. Gbogbo wọn ni nwọn nlọ si ibi iṣẹ, ṣugbọn ijoko tẹtẹrẹ ni gbogbo wọn wa.

Onirohin wa kan fi ye wa pe, awọn ọkọ oju-omi mẹrindinlogun lo ti de si Apapa lati ilu Oyinbo ti nwọn ko si ri awọn oṣiṣẹ lati ko awọn ẹru inu wọn silẹ.

Awọn Oga ọkọ oju omi meji ni nwọn binu kuro ni Naijiria ti nwọn si lọ ja awọn ẹru inu ọkọ wọn si Ghana, ṣugbọn a gbọ wipe nwọn fi mọto ko awọn ẹru na wa si Naijiria pada.

Gbogbo awọn ọja ni nwọn ti tun fi kun lẹhinti awọn oṣiṣẹ da iṣẹ silẹ yi.

Lati ọjọ ti awọn oṣiṣẹ ti da iṣẹ silẹ awọn enia ko ri inu Lẹntriki lo da a d a mọ, abẹla ti ẹlomiran ti lo ju owo ti nwọn nsan ni oṣu fun ina lọ. Awọn ti nlo atupa ti fẹrẹ lo to epo Oyinbo garawa kan.

Gbogbo awọn ọja lo ti gbe owo ka ori ti omiran ti fẹrẹ rekọja idaji. Iyọ agolo kan di sisi, ẹran sile meji di sile mẹta lọja, awọn ti o npa ẹran meje ko le pa ju ẹran mẹrin lọ, awọn ọlọja ko tilẹ wa ri owo ra ọja si igba, awọn to ni ọja nigba ko ri ẹni wa ra wọn,

ỌRỌ ITIJU

Onirohin wakan fi ye wa pe Ijọba ko kan leso pe " awọn fẹhinṣilẹ fun awọn oṣiṣẹ ni, ki ọran wa ki fo, maṣe bọsi itiju ni wọn ṣe sọ pe, awọn oṣẹjipade lori re, ki awọn oṣiṣẹ pada si ẹnu iṣẹ wọn na.

O tun fi ye wa pe " ọran ti ṣu Ijọba, nwọn ti gba lati san owo oṣu na fun awọn oṣiṣẹ loni ninu ipade ti wọn, fẹ ṣe,,.

Onirohin wa na sọ pe " Bi Ijọba' ko ba gba ohun ti awọn oṣiṣẹ wi' awọn oṣiṣẹ tun le da iṣẹ silẹ lẹhin ipade ti nwọn o ṣe ni ni o

Bi nwọn ba ti pari ọrọ ẹkunwo owo oṣu ti awọn Minista fun Apapọ Ijọba a t i awọn Asiwaju ẹgbẹ awọn oṣiṣẹ ti nwọn fẹ ṣe ni oni si, ẹ o ma a gbọ ẹkunrẹrẹ irohin na ninu iwe irohin wa ni ọla.


THE ANSWER TO

TROPICAL CONDITIONS

★

UNMATCHED

AFTER SALES

SERVICE

★

MERCEDES-BENZ



LEVENTIS MOTORS LTD.

LAGOS, APAPA & EBUTE-METTA, IBADAN, KADUNA, KANO, JOS, ENUGU, ONITSHA, PORT-HARCOURT & ABA.



Printed and Published by Modupe Printing Press 16, Bamgbgose Street Lagos Phone 21985
Editor TUNJI ADEOSUN 45, Campbell Street, Lagos (15/6/64)